ASOJE ORO

Bi a ba wo gbo gbo arun ti o nseku pa eda, se owo ara wa l'o ti nwa ba ni, Olorun ko da jakute beni ko da warapa, ohun ti a ba se l'o nfa iku ba ni.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

IWE YORUBA

Wo ... ofe ... ni ... iye oju to ba ... l'orun.

Ko dun mi, ... agbal gba mbo ... A ki ... pa l'oso.

VOL. XII No. 680. LAGOS, SATURDAY, JUNE 18, - JUNE 24, 1960. KOBO MEJI (2d)

# MECCA ODUNNI REBENTE!

## EGBARUN EMI L'O SOFO SI AJI.

MEDINA. Oluwa Olorun ni o pa ni ase fun gbogbo Musulumi wipe enikeni ti o ba gba esin Anobi Muhammed gbo, ti o si ntele suna re, oranyan ni fun oluware ki o lo si ilu Mecca lati se asepe esin re. Idire re ti ogunlogo awon Musulumi jake-jado agbaiye fi nlo si ilu Mecca ni ododun.

Sugbon ni ododun ti awon enia wa nrin irin ajo wonyi ni a ma ngbo oriṣiriṣi irohin okankojokan nipase amodi bi ilegbona, aare okan, Oyi, ati amodi bi Onigbameji. Ni ododun ni a ma ngbo iku awon enia ti nwon lo silu Mecca yi, sugbon irohin ti odunni rebente, o pa bambari, o si bani ninu je gidigidi, nitoripe awon oriye enia po ninu awon ti o ku ni odunni.

Ninu awon enia pataki ti a gbo pe o ku wonyi ni Alhaja Ayi Kenku, Alhaja Sinatu Elias, Alhaji Mufutawu Bakare Aloboh ati Hadji Akoshile ati Hadji Umoru, Oba ilu Nasarawa nile Oke Oya. Ki Oluwa f'ori jin won, ki o si gbe won si afefe rere. Amin.

Awon Alhajaja ati Alhajaji yio bere si pada de lati ojo 16th titi de 23rd Osu June, 1960, yi.

## Idapo Sokan Ile Afrika koiti Ya

Malam Maitama Sule ti o se akonile awon ti o lo si ipade gbogbo awon Orile ede ti o wa nile Afrika silu Abyssinia so ninu oro re lohun wipe idapo sokan awon Orile ede Afrika ki ise asiko isisiyi, nitoripe lasiko yi awa nile Nigeria kole fara mo idapo pelu orile Afrika miran ako ie fi ijoba wa si abe ijoba miran.

Awa ni igbagbo pe opolopo ile Afrika ni yio fe se ijoba funra won ki nwon o si gbadun ominira lehin ti nwon ti wa labe ijoba ajeji fun ojo pipe. Ati pelupelu, awon ilu Afrika miran ko fe se ohun ti ilu Nigeria ko ni le faramo.

Ki a to le se idapo orile ede ti o mbe nile Afrika, awon le yan irufe eyiti ile Liberia fe lasiko, eyun ni "Egbe Orile ede Afrika.



MALAM MAITAMA SULE
Oun ni o se asiwaju awon ti o lo se ipade ni Addis Ababa.

## Tembelekun Tun Be Sile Ni Mosalasi Jimo, Eko

Edekoyede kan be sile lori oro aga Alufa Tafusiri, larin ijo awon Lemomu Ratibi, ati Lemomu Jamiu ninu Mosalasi ela ti a npe ni Mosalasi Jimo, nilu Eko lati ose kela sehin wa.

Ni Jimo keta ti o lo lohun, 3rd June, 1960, ni baba wa, Ogbeni Sulu Shitta ti ise Seriki Musulumi fun gbogbo awon omo Islam ni Eko, fi ase si pe, Alufa Kofoworola Yakub ni ki o gun ori aga tafusiri ni odun ni. O si fi a le baba wa Alhaji Sadiku Sarumi lowo wipe ki o se gbogbo eto ti o ku.

Sugbon bi gbogbo awon eto na ti nlo, beni awon kan ti tembelekun oro lselu bo eto sisa Olorun yi. Ni gbogbo ojo Jimo ni oro na ntobi si, ti o si ngbero.

A be Olorun pe ki Oluwa dakun petu si oro yi ki o to di eyiti apa ko ni kamo.

## Alase Ile Igbimo Nla Ile Nigeria Nilu Amerika



Alase ile igbimo nla (House of Representatives) ti ilu Eko, Ogbeni Jaja Anucha Wachuku ti o lo be igboro ilu Amerika wo so wipe ofin ilu Amerika dara, o si tile koni leko pupo.

Ohun ti o mu lati soro yi jade ni wipe o lo se abewo won nibiti nwon gbe mba ara won to pero nipa ofin, o si fe tan igbimo nla (Senate ati Representatives) ti ile Amerika.

## Ipinle Ila-Orun Ti Di Ilu Oloba Nisisiyi

Ni agbegbe ipinle Iwo-Orun, orisirisi awon oba lo wa nibe, nla wa, beni kekeke wa pelu, olokiki wa, beni ni eyiti ko ni okiki. Ni oro kan, bi ilu kan ba ti tobi to beni okiki re se nkan.

Gegebi o ti ri ni ipinle Iwo-Orun, bakanna ni nile awon Hausa ni Oke-Oya.

Sugbon ni ipinle Ila-Orun, ko si Olori ni Aganyin ni won, gbogbo won lo ngbe iga akan. Nitorina ni awon ara agbegbe na ko se mo iyi oba, nwon ko mo bi ati se mbu ola fun oba tabi ki awon ye oba si.

Nigbati awon de ilu elomiran, ti nwon ri pe, ohun

(Wo yoku loju ewe kejo)

# Ipade Ile Afrika Nilu Ethiopia

Ọba Hailu Selassie oba ilu Abyssinia pe ipade igbẹ ... ilu ... ekanla ati ... o sọ lori ilu Afrika ti awọn ti gba ominira ara wọn wipe ki awọn pade ni ilu Ethiopia ... eto pataki kan ni.

Orisirisi awọn ... ile Afrika, awọn le ni adota-lelọgbọn ... le si ipade na ni Bandung, ... ipade na. Nwọn ṣe ipade na nitori ile igbimo ... kan ti Ọta ... nilu Ethiopia.

Awọn diẹ nwọnyi ni nwọn ṣe akiyesi wipe nwọn ko wa si ipade na bẹni nwọn ko si ran aṣoju wa, ilu Togoland, Madagaska, Mali ati ilu Belgian Kongo.

Awọn ara Kongo ... ni wa wipe ọrọ ilu wọn ti koiti fi idi joko nipa ominira ko jẹki nwọn le fi ilu silẹ.

# Bami Kerin Die

Obinrin Onigowo kan lọ ra ... ni ilu kan, ko si mọ pe ... ko gbọdọ de ibi ti o de na.

Orun mu, o si ... o joko ni ... kan, o si ki ... ti o mu ... ni ... lara.

Bi ... ni ... wọ inu de, o duro, o nwo o, ... ekẹta, ekerin, nigbati ... de ni obinrin na so wipe ... ni ... bayi ẹwẹ, ṣe ko si nkan?

Awọn enia na dahun pe ha-a-a, tabi alejo ni iwọ ndan? ... ri wo ni, bẹni obinrin na si mọ ọ ti o si ba tire lọ. Hi, Hi, Hi, Hi, Hi.

Awọn ọlọpa mu ọkunrin kan nwọn si fi ... pe o lọ fọ Banki o si fi ... apoti owo.

Ọlọpa na dahun pe, bẹkọ ni ... ri Oluwa mi, emi ko fọ Banki ṣugbọn nigbati mo si ... owo ti ko ṣe ... mo ... lo ... fun ... ha, ha, ha, ha.

Ọkunrin Fulani kan ri pe ọkan ti ... nwọn ... re, o wa ... Bi o ti ri bi ... kan, bẹẹ o ri okunrin kan ti o mbo ... kan ti ... ti ... o wa ke si ... na, o pe Hi! ... na, ... lo ji malu mi, ... o.

Oti na dahun pe ... malu re, ... mi ... mo fẹ yo ... lara re. ... ho, ho, ho, ho, ho.

# America Fi Ododo Oro Han Igbimo Nla

Nigbati awọn igbimọ ... Senate (Senate Foreign Relation Committee) ṣe ipade, nwọn bere lọwọ ara wọn wipe, kini ohun ti o le mu awọn Rọsia lati ma ... pe, awọn ... ọkọ ofurufu wọn U 2 ... nitoripe o ... ofurufu ... wọn?

Ọgbeni Christian Herter ti ... akọwe agba fun ilẹ Amẹrika, dahun pe, awọn olofofo ara ilẹ Rọsia ti o mbẹ ni gbogbo agbaye ... ọkọ ... ara ilẹ Rọsia ti ... ti ba, ti nwọn si mbẹ ... yi. Ogun ... wọn ... wa ni Western Germany.

Awọn Rọsia ti ṣe ... kan ... fi wọn ti ... ti ... abajọ!

# Owe Yoruba

**BI ẸBITI KO PA EKU YIO FI EYIN FUN ẸLẸYIN. ẸHINKULẸ NI ỌTA WA ILẸ NI AṢENI NGBE IREPO NI OGUN AIYE**

# OMOBA BINRIN ILU MOROKO LO BE EGBE RED CROSS WO



Ẹniti a nwo ti o duro ni apa osi ninu aworan yi ni omoba binrin ilu Moroko ti oruko rẹ njẹ Fatima Sahara, ti o si jẹ iyawo fun Ikọ-oba (Ambassador) ilẹ Moroko nilu London. on ni okan ninu awọn osiṣẹ Red Cross nfi awọn aṣọ Bulankiti ti awọn ako lo fun awọn ti jamba ṣẹlẹ si nilu Moroko ati Mauritius han.

# Ijagboro Be Sile Nilu Kabba

Agbọ irohin wipe ijagboro kan bẹ silẹ larin awọn ara ilu Kabba si ara wọn, to bẹ ti o jẹ wipe, nigbati awọn ọlọpa ijọba ibilẹ ba wọn lọwọ si ina ija na, iwọn ọgọta enia ni nwọn ramu, ti nwọn si ti mọ ile.

Ija na ṣẹlẹ lori awọn enia meji ti i ndu oye, ni adugbo kan ti nwọn npe ni Ifẹ-olu ọkọtun ni apa Ila-orun ilẹ Yagba. Agbọ wipe, ija na dabi eyi ti nwọn gbe ogun ti ara wọn, nitoripe awọn nlo ada, kondo ati kumọ, gẹgẹbi eyiti nwọn mbẹ loju ogun, ọgbọn enia lofi ara gbọgbẹ, ti oju ọgbẹ wọn si lewu, nwọn yara ko wọn lọ silẹ alaisan ti S. I. M. nilu Ẹgbẹ. Ṣugbọn awọn yoku ti oju ọgbẹ tiwọn ko lewu, nwọn ko wọn lọ silẹ alaisan nilu Isanlu.

Larin ibiti nwọn nja ijagboro yi, awọn kan njẹ'ja, nwọn nfọ ile, awọn njẹ dukia run. Wakati meji ni nwọn fi ja ija na, ilu ibiti awọn ọlọpa ti wa de si ija na jẹ irin ogoji buso lati

(Wo yoku loju ewe keje)

HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan ... Amulets, ... Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

HINDU SANKARA, ... Row, ... London, ... England

# Nigerian Ports Authority

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period 1st July, 1960, to 31st December, 1960, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay, or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa area.

2. Tenders indicating a price per ton should be submitted in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP" and addressed to the undersigned so as to reach him not later than Wednesday, 22nd June, 1960. Late Tenders will not be considered.

3. The successful tenderer will be required to remove, at his own expense, whatever scrap is available for sale (with the exception mentioned above) during the six month period indicated, within 7 days of the Authority's notification of such availability and will be required to make the necessary arrangements at his expense for all the scrap removed to be weighed in the presence of a representative of the Authority.

4. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

**BAYO KEHINDE**
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice NO. 440.
10th June, 1960.

## Oro Ile Fe Da Ogun Sile Ni Onitsha

Edekoyede kan be sile larin Idile Ogbo ni Onitsha ati awon ebi Obosi. Ohun ti a gbo pe o fe da ija na sile ni ile biri kan ti awon enia kan fe kole si lati ma gbe.

A tile gbo pe, awon ti ko bi iwon odunrun ile ni awon spakeji to mu Olopa ati Sirifi lo sibi ile na, ti nwon si bere si wo ile danu.

Nigbati awon gbe elo na de Keto, adsie de awon Idile Ogbo Isre, eyi ni o mu nwon gbe Olopa ati Sirifi ti nwon si elo wo awon ile na subu.

Ki ko le si ogun Olopa ti nwon ti gbe dide, ija na iba di ogun ti a ni di ode. awon Olopa ti bere si ko awon idile Ogbo ati Idile Obosi Oro na koiti pari sibe, awon olopa si nse lati ile de ile lati ma se awon ti o lowo ninu ija na. Eno re ni nwon si wa.

## Awon Ara Mushin Nfe Ilosiwaju

MUSHIN: Nsin loade Oniwe irohin ti Ogbeni Kumuyi pe ninu ose yi, o so wipe ko si ilo siwaju kankan ni ilu Mushin fun awon ti o ngbe ilu na, ati gegebi o ti le wipe ilu Mushin ni ilu ti o tobi sikeji ilu Ibadan ni abe Ijoba Iwo-orun, o to, o si ye ki Ijoba Iwo-orun se eto awon nkan anfani si ilu Mushin, paapa ti o je wipe a ngborun ominira ile Nigeria wa yi.

Ogbeni Kumuyi tun te siwaju pe awon tu igbimo ibile ilu Mushin ka ninu osu April, ti nwon si yan awon enia pataki fi se alabojuto re, sibe ko si eto tabi ise kan ti o le deedee nilu Mushin. Bakanna ni Alashe ilu Mushin Onile Mushin Ojuwoye ati Oloye B. M. Dosumo ti Ikorodu ati Ogbeni J. A. Odu na soro lori aiko si ilosiwaju ati ohun anfani fun awon enia ilu Mushin.

Ogbeni Kumuyi tun fenu ba oro oye jije to nda rogbodiyan sile ati temheleku nilu Mushin o si so wipe ki awon iwe irohin ba awon ba awon enia ilu Mushin gegebi o ti je pe asiko ti a nfe gba ominira yi o ye ki Ijoba Iwo-orun ba wa mojuto atunse ilu Mushin.

## Dokita Ko Po To Nile Nigeria

Dokita Nwokedo, ti ise okan pataki ninu awon Onisegun ti o nsise ninu ile iwosan so wipe, aisi awon Dokita to ni ko jeki ise isegun ti ni ilosiwaju nile Nigeria yi.

O so ni ilu Enugu pe, ise isegun ti oyinbo lo je eyiti o tehin lojo nile Nigeria ati ni gbogbo aiye, nitoripe awon Dokita ti o wa ninu wa ko po tebe rara.

Ohun ti o dara ni wipe ki Ijoba alapapose ma ran ogunlogo awon omo akeko lo silu oyinbo lati lo ko ise yi lododun. Bi Ijoba ba si tele imoran yi, nigbati yio ba fi di opin odun 1965, ao ni awon Dokita ti o po to egbarin nile Nigeria.

Eyi je imoran rere ti Dr. Nwokedo gbe siwaju Ijoba Apapose, o si ye ki awon tele imoran rere na, nitori opo ni awon olokunrun ti o nfe itoju. Ise po sugbon alagbase koto nkan

## Itan Bi Serafu Se Bere Nilu Eko

(Apa keji) Lati owo Aladura

Ise kini ti Moses Orimolade se nigba aiye re ni wipe, o fi nko awon omo egbe re lokunrin ati lobinrin gegebi a ti se ngbadura gegebi Onigbagbo. Awon omo wa ko mo ti enigbagbo ti se ngbadura ati bi awon ti se nlo Iwe Orin Dafidi ati gegebi enia ti se npe Olodumare ti o fi nje.

Ako so wipe awon ko ngbadura ninu Sosi, sugbon ko dabi igba ti Baba Aladura. Ise keji ni wipe, o nko awon omo ehin re gege bi a ti se aki Olorun, Eketa o nko awon omo ehin re gegebi a ti se ngbadura ati Awe.

Ekerin, Orimolade nko awon enia gegebi a ti se nlo ife si omonikeji eni, lati ma ran ara eni lowo ninu ohun kohun ti o ba de baai, nwon si nfe ara won lo po bi omo iya kan. O ko won bi enia ti nwa ni mimo, ati bi a ti nse alafia.

Ohun pupo ni ise iyanu ti o farahan ninu egbe Serafu, awon iriran, awon ami asotele, awon nmu Olokunrun ni ara da, ati nigbati awon bi nkorin, awon o ma lulu, awon o si ma jo. Koiti pari, lose ti o mbo ao gbo bi Capt. Abiodun se da ise ijo na.

## Ojo Idibo Kamarun Di Osu Feb, 1961

Bi a ba ndaruko Southern Cameroon, iyen ni wipe ilu Buea ni a nwi. Ilu Buea ti a si wi yi ni ibujoko ijoba Gesi, ibe ni ibujoko Asoju ile Kamarun. A si ti gbo wipe gbogbo awon akowe Ijoba ti o wa ni ilu Buea ti a wi yi ni awon ma da pada sile Nigeria ki osu August to le.

A gbo wipe awon ara ilu ti a wi yi ko fe kuro labe Nigeria, nitorina ni awon Olopa ko se ni tete kuro ni ilu na. A ti gbo wipe

( Wo yoku lojú ewe kefa )

# ELETI - OFE

A-NJUWỌN KO ŞE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 28, Kosoko Street, Lagos — P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM — "ELETI - OFE, LAGOS" — Phone 23370

VOL. XII. NO. 670. SATURDAY JUNE 18, – JUNE 24, 1960


## Akojo Owo Ni Afi Nsoiya

Ki awọn ọkawe wa şe gafara fun wa lori wosika wa ọsẹ yi, nitoripe owe fẹrẹ po ninu iwe wa na, bẹ ko si le şe alaimbẹ nigbati awọn Yoruba mọni-mọni sọ wipe "Owe ni eşin ọrọ, bi ọrọ ba sọnu owe ni a fi nwa," "çsik o ki ida agan gbe," nitorina ni a şe fi wosika wa yi şe itaji fun awọn aşiwaju ẹsẹlu wa ti awọn şe eto Asia ati Orin ilẹ wa Nigeria yi, eyiti ao ma lo lẹhin ominira wa.

Iba şe wipe awọn igbimọ eleto ti o şe eto Orin ati Asia na fi aworan rẹ han gbogbo-gbo, ki awọn enia si şe ariyanjiyan lori wọn, ki awọn to mu eyiti ohun ọpọ enia ba jọ le lori, a ni ero wipe irufẹ atako ti awọn enia da oporo rẹ bo iru eyiti awọn yan fun wa wọnyi ki ba ti waiye rara.

Nitorina, o yẹ ki awọn igbimọ eleto ma fi ohun ti o ba jẹ ti ilu, paapa, ti gbogbo ilẹ Nigeria han awọn enia ilu ki awọn to mu eyiti ọpọ enia bafi ohun şọkan le lori.

### IRANŞẸ KOTU YIO GBA AGBARA LATI MU ENIA

Igbimo ijọba ibilẹ awọn Isobo şe igbimọ kan laipẹ yi, ninu eyiti awọn fun Iranşẹ Kọtu ( Court Messenger ) ni agbara lati ma mu enia gẹgẹbi ọlọpa ni apa agbegbe ilẹ Isobo ti o wa ni Iwọ-orun, gbogbo igbimọ lo fi ara mọ ofin na ti awọn si gba bẹ.

Awọn igbimọ yi tun panupọ awọn yan ọba Orodje ilu Ope Ẹsrọi Keji, ni alaga igbimọ wọn nigba keta.

Şugbọn awọn şe alaye wipe "Ira ti o ba şe ni ọba ama" awọn ko gbọdọ gbọ wipe, iranşẹ Kọtu na mu alaişẹ ki o si ni şiçu ti o le jẹri wipe odiọ ni ọdaran na şe.

### Oko Balu Ko Lati Wale

CHICAGO Awọn jẹganjagan oju omi ta Balu (Balloon) kan si oju sanma lati fi dan awọn ohun ija kan wo, nigbati awọn ta balu si oke orun tan, ti awọn ti şe ohun ti awọn fẹ şe pari, nje ki oko Balu nbọ nile, itọ! Kanla ki o wa ile, nşe lo tunbo ngun oke orun lọ.

A gbọ pe nisisiyi, ibiti Balu na gade lo ibiti ogoji petesi le ga de. Nwọn ni ki awọn enia ti o wa nibẹ ma şura ki awọn da ogbọn si.

Adota ọta agba ibọn ni awọn ni awọn oko ofurufu yin si balu na, kaka ki ẹfufu inu rẹ jọ kojo kaka bẹ nşe l'o tun nga si oke. Awọn ologun oju omi so wipe awọn ohun ija wẹwẹ ni awọn nlo lati fi jẹ Balu na lele, ni toripe bi awọn ba lo lo eyiti o lagbara ju bẹ lo, yio run gbogbo Balu na womuwomu yio si ba awọn ukan oniyebiye ti o wa ninu rẹ jẹ.

### AWON ARA BENDE NILATI MA MU IWE OWO ORI RIN

Ogbeni E. U Esalen ti işe Olori awọn akowe olowo ori so wipe owo-oriti ijọba fẹ gba ni ilu Bende ati agbegbe rẹ ku £8,687 ti o pe ogun logo awọn enia lo afi ori m'okun ti awọn ko fẹ san owo ori tiwọn. Bi awọn ba si bere lowo won pe owo ori won ako? ẹlomiran le dahun pe o mbẹ ni buso marun, mefa tabi meje.

Nitorina, igbimo awọn olowo ori şe ikilo wipe, enikẹni ti o ba nlọ si ode idalẹ tabi si ajo ki o ma ma iwe ti o fi san owo ori dani.

Enikẹni ti awọn ba bere owo ori lọwọ rẹ ki awọn yọ eyiti awọn gba nigbati awọn san owo ori fi han enitI ko ba le yọ iwe ti o fi san owo ori han, ọlọpa yio sogbagi nidi rẹ nwọn o si fi si itimọle.

### JAMBA MOTO AKERU ŞELẸ

Moto akeru kan ti awọn fi ẹru ekuro ni kun-dẹdẹ lati ilu Ibadan ti o mbo nilu Eko. Nigbati o rin bi buso merinlelogun ni ona Abẹokuta silu Eko ni akẹru nla na yi şubu sinu kote enitan pẹlu ti o wo oko na gẹgẹbi ero ni o ku sibẹ lẹsẹkẹsẹ.

Oruko ero ti o wo oko na nje Alfred, Obasoji, o to ọmọ odun mọkanlelogun, oku re wa nile Iwosan ni Ikeja. Awọn ọlọpa ti şe iwadi lodo Awọmoto na.

## Oba Gesi Fi Oye Nla Da Oba Olowo Lola



Inu wa dun gidigidi nigbati a gbọ wipe Alaiyeluwa, Elisabeti Keji, ọba Gesi fi oye nla (Knighthoods) da Alaiyeluwa James Titus Ọlagbegi Keji, ọba ilu Owọ l'ola.

Ọba Olowọ yio di ẹni adọta ọdun ninu oşu August. O di awọn oba pataki mẹta nile Yoruba ti oba Oyinbo fun ni Oye nla yi.

(1) Sir Ademola, Alake ilu Abẹokuta. (2) Sir Adesoji Aderẹmi, Ọni Ile-Ifẹ, ati Sir James Titus, Olagbegi Keji, Ọlowo ilu Owo.





## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajẹla ọmọde agbomọla bi erişa, akẹkọluko ogun ti ndamọ l'ekun igbona, atata ogun ti npa otutu rẹ warawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abiku di ikugbagbe, o ş'ọmọ ti nhein l'ore, ikọ ri i sa, iba ko l'ọna tagiri, aiperi ri d'ẹkun iyọnu Olugbala f'ọmọ ti nyagbẹ ọrin o kapa ino wọ, o lu jedi l'alupa gbogbo abiyamọ nyọ ẹcẹẹ Ela ri i o roju, Ọrẹrẹ ri i o sa' gbẹ bo ra Eyi npa lọmọ lo dilọọ, ọrẹ ikoko, koşemọni awọn abiyamọ, ẹni araiye njijadu ra. O de ilu Ibo, o doga, o de ilẹ Hausa o d'ọba, gbogbo Onişegun l'o ro pe ko lẹgbẹ gbogbo ọmọde lo nfẹ ẹ fun ilera.

IGO KEKERE 2/6d

IGO NLA 4s owo ẹkọ lọtọ.

THE ẸGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street

P. O. Box 2 Ebute-Metta.




## Awon Ojogbon Onisegun Pa'na Arun Ni'le Afrika

A ti agbo leue awon alegba wipe arun ko mani owo, ko si eni ti ko le lolu. Nigba atijo, eru jeje lo ma nje fun awon Oyinbo nigbati eeikan ba da oruko agbegbe Iwo-orun ile Africa, nse ni nwon o ta giri wipe ha! Ilola! ise oku awon alawo funfun.

Nigbana, bi Oyinbo kan ba wa sise ni Iwo-orun Africa, bi o ba gunle si Eko, yio si ma dun, bi o ba kuro nile Yoruba, efufu yio yi pada, bi o ba tun de Kaduna yio tun yi pada, iru aken bayi lo nko ugpacte ba awon Oyinbo ti o si npa won nigbana.

Awon omode nku pupo nile Ghana ni akoko ne, ida mokanla ninu ogorun pere ni o fi sanju ile Nigeria lo. Ni akoko na, oturu, ako-iba ponju poju wopo gegebi ile British Guiana.

Alaiku ri onje jeko njeki awon omode miran ri alafia. Alafia de ti wako gunle si ile Ghana ati Nigeria lehin ti ogun pari, o si daju pe be ni yio ma ri, ko si tile si idi re ti ko fi ni ma je alafia lo titi.

---

## Awon Soja Ile Nigeria Pada Wa Sile

Awon omo ogun ile Nigeria (4th Battalion of the Queen's own Nigeria Regiment) ti nwon ko lo sile Kamerun lati di gaga fun awon ara Isale Kamerun, nigbati rogbodiyan be sile larin awon ara Kamerun ti o mbe labe asia Gesi ati awon ti o wa ni abe asia Faranse ni a gbo wipe nwon ti pada si ilu Ibadan.

Onirohin kan fi ye wa wipe, awon omo ogun na fe yo ayo lilo ti nwon lo lo ti nwon si bo re nitorina nwon fe jo ijo Soja kakiri igboro Ibadan lojo Saturday oni yi 18th osu June, 1960. Dr. Majekodunmi ni yio ki awon omo Ogun na pe nwon ku orire ti ko si ikolu tabi ikoleru.

Ori gbogbo enia ni yio wule nigbati nwon ba gbo ti awon soja ba nfi fere ko orin bayi pe:-

Mo lo s'ogun mo de,
Mo lo s'oja mo bo.
Ogun ko pa mi,
Mo jakaragbado,
Mo j'okuta meji.

---

## Adajo Ko Ejo Masilina

Obinrin ara ilu Owerri kan ti o nje Masilina Osua gu ni a gbo wipe awon olopa ramu ti nwon si fi sun esun wipe, o sesi pa enia, adajo ko'u Owerri si dajo fun pe bi o ti je wipe nse ni

(Wo yoku loju ewe keje)

---

Kere o!

A ti ni orişirisi egbogi fun arun inarun ati arun Jedijedi (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tire, t'okunrin ati t'obinrin ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORE
7 Egerton Road, Lagos

Reduced Freight Rates !!!

Your business will benefit in
1960
by using the Railway

x x x

A special rate of only 34/- per ton has just been introduced for ALL commodities from

Lagos, Apapa, Or Iganmu
to
Oshogbo

Previously you paid between 36/- and 181/- per ton for goods,

x x x

Save money now by using rail transport which is save and reliable

The Best Way Is The Railway

HAVE YOU ANY TRANSPORT PROBLEM ?
IF SO, CONTACT OUR
RAILWAY LIAISON OFFICER
TEL. LAGOS 44245.




# Tani Le So Pe Iya Oba L'aje

(Apa Keta)

Egungun Polo sọ fun ọba pe ki o lu agogo wipe, ni ọjọ meje loni on yio jade. Nigbati ọjọ pe, ẹsẹ gbogbo enia ti pe si afin ọba ni isọri-isọri, awọn gbajumọ, awọn Onidan, awọn Iyafin, awọn ọlọmọge, awọn Dankare, awọn ọmọwẹrẹ, Ọjẹ, Apena, Olegun, Ajana, Balogun, Surepegbe, Mayẹloye ati gbo gbo awọn enia bawọnni.

Ilu bata ndun kikan-kikan, nigbati o ṣe ni Polo de, bi o ba njo, a ma ṣebi eyiti yio fi aake ọwọ rẹ ṣa enia, ko si ẹniti ko nṣe bẹ fun. O nṣe si Ọba, o nṣe si ojoye, o si nṣe si Iyalode ilu.

Nigbati o ṣe ni egungun na nsare bọwa, o wipe, Iya ọba la-a-a-o? nigbati ọba gbọ bayi, o dide fuya, o wo rarara, Polo ṣebi eyiti yio fi ake ṣa iya ọba, o tun pada sẹhin.

O tun jo lọ siwaju, nigbati o ṣe, o tun si aake mori, o nsare bọwa, o nwipe, iya oba la a a o? Otun ṣebi eyiti yio fi aake ṣa Iya ọba, ara ọba tun gba ina' o ṣebi o fẹ pa Iya on ni. Ko si ẹniti o le dahun ninu gbogbo Ọjẹ Polo tun pada lọ ni eba kete, o tun si aake mọ ori o nsare bọwa o nwipe, Iya ọba la-a-a-o? Nigbati ko si eyi keyi ninu awọn Ọjẹ ti nwọn jijọ ṣe adehun pe awọn yio dahun pe Iya oba laje, ti gbogbo wọn pehan nigbati nwọn ri oju ọba.

Nitori na nigbati Polo pada de iwaju Iya ọba, o ni ki onilu Bata fi ilu si, o nwipe Iya ọba lalubarika ni mo ma ma wi o, ni onibata ba fi ilu si bayi pe, nla ode-kan nti de kan nti de kan de kan nti nla de kan nti. Ibẹ ni agbo ba fọ Eyi na lo di owe ti nwọn npa loni wipe Jẹki awọn gbọ ẹnu rẹ pe Iya ọba ni aje.

---

## ỌJỌ IDIBO KAMARUN DI OṢU FEB 1961

(O bere lati ewe keta)

awọn ẹgbẹ jagunjagun kan ti de lati ilu oyinbo ti yio rọpo awọn Ṣọja ti o wa nibẹ. Nigbati o ba di ọjọ 11th Feb, 1961 ni awọn o tọ ibo na di lati mọ ẹbẹ tani awọn fẹ wa. Faranse ni tabi Nigeria, nitoripe awọn ni eyiti awọn ba di koja lọ mu ọwọ ojoro dani.

## Olorun Ko Roro Ko Fi Esin Imale Ni Enia Lara

Lati Owo Alufa Abdulai—Deen

Ko si ohun meji ti Olorun da wa sile aiye fun o ni ki a ma lo sile aiye, ki a ma je, ki a ma mu, ki a si ma sin On Olodumare ni ona ti o ro wa lorun gegebi ilana on.

Bi o ba fe sin Olorun, sugbon nitoripe iduro je inilara fun o, ko ni jeki o sin Olorun na, joko sile ki o sin i. Bi ijoko ile ko ba sese, joko lori apoti tabi aga pataki ti o wa nibe nibe ni o npe ki o sa kirun na lona ti o ro o lorun. Enia le kirun ni iduro, ijoko ifegbero, ati ni idubule. Sa ri wipe o sin Olorun lonakona.

Bi o ba di karangida, ti a ba fi agbara mu enia duro niwaju orisa lati sin i ati pe bi oluware ba ko lati se be, nwon o pa oluwa re, ki o fi okan daniyan wipe Olorun ni on nsin, nitoripe okan ni Olorun nwo, o si ni mimo gbogbo awon ti o nsin i ni ododo.

Olorun ko so wipe tulasi ni irun Nafila, eyiti o je pataki ninu awon Nafila ti a nyan ni meji, ki a to kirun Asubo, meji lehin Ayila, meji lehin Mogaribi ati meta lehin Lissyi. Gbogbo awon Nafila ti a daruko nwonyi lo ni oruko ti nwon npe e.

Eniti o ba fe le yan egberun Nafila, nse ni oluware yio gba lada tabi ibukun. Bi o ko tile yan okankan rara ko nse ese. Bi enia ba fe yan Nafila lati fi wa ibukun, patapata re ki o mase tayo rakaa merin salamo meji. Bi o ba si je alare okan ti iwo ko ni suru lati yan tobe yan rakaa meji salamo kan.

Sugbon bi enia ba nfe nkan lati odo Olorun, o le yan egberun nafila nitoripe o fe fi Nafila na fo ara re mo niwaju Olorun ni. A ko gbodo kirun nafila tan ki a ma fa tesuba subuhanalai 33 Alhamadulai 33 Alahu-akiber 33. Enia le kirun Nafila tan ki o si bere asalatu tabi ki o ma kewu miran ti o yato si kewu ti a fi nfa tesuba.

(Wo yoku loju ewe kejo)

## Eniti O Se Fayawo Wo Tuwon

A gbo irohin pe okunrin kan ra agolo siga Craven "A" 1,588 ati agolo siga Consulate 1,268 ati agolo siga Capstan 1,268 apapo gbogbo owo re le ni £1, 664, o fi gbogbo awon eru nwonyi se fayawo, ko san owo bode lori re, ni olopa ba ramu.

Awon olopa fi ejo Okunrin Onifayawo yi siwaju adajo, o rojo funra re o si jebi esun na adajo ni ki o lo si ewon osu mejila nitori ti o se ifayawo.

## Adajo Ko Ejo Masilina

(O bere loju ewe karun)

oro na sesi lowo re adajo ni ki o lo si ewon odun mejila O kigbe gbi ! odun mejila tan rara o, Nko gba, emi yio gbe ejo na lo si kotu kotemilorun,

Bi oro na ti lo nisyi Masilina ati Rosana je aya oko kanna, Osuagu ni oko nje. Sugbon nigbati ija de larin awon obinrin mejeji a gbo wipe Masilina lu Rosana pa.

E/o Apanis ni awon olopa ti koko mba obinrin na ro tele ri, ki adajo to wa yi si wipe o sesipa enia.

O fere to odun kan ti awon ti nro ejo na ti ewon ni egbe ju sile. Adajo kotu kotemilorun so wipe, dandan ni ewon odun mejila na ki o lo gbewa ni ogba Nogeji.

## IJA GBORO BE SILE NIILU KABA

( O bere loju ewe keji )

ilu kan ti awon npe ni Isanlu Mokutu.

Bi ija na tise bere niyi: Agbo wipe Ijoye kan ti nwon npe ni Shaba lo ayo ayo odun Ileya, o nlu ilu, o si njo, on si ni igbakeji oba. Bi o ti njo yi, beni ijoye kan ti o ti mba Oloye Shaba du oye ba pakuru mo nibiti o gbe njo, ibe ni ija ti bere. Onilu sale, Olomele pa ilu re mo abiya o si fe e kito.

Olopa ni wipe, gbogbo awon enia bi ogota ti owo awon te, nwon yio ko won lo siwaju kotu ijoba ibile Yagba Isipe.

# Oba Obinrin Da Asoju Ile Nigeria Lola



Awon meta ti a ri awotili o duro papo ninu aworan yi ni awon asoju meta lati ile Nigeria. Eniti o wa larin, mei won ni Alhaji Abudulmaliki ti o nfi oye C. B. E. ti Oba obinrin Gesi fi da lola han Malam Abbe Jidun Gana, ti o duro lowo osi ati Ogbeni Ade Martins sekiteri akowe agba fun asoju ile Nigeria.

POLOWO OJA RE SINU IWE IROHIN Eleti-Ofe

## Ibere Ati Idahun Nipa Commonwealth

IBERE—Nigba-gbogbo ni a ngbo to tobi ti a ma nsaba ... iwe iroyin wipe Commonwealth se fun wa. Ohun, kini awon apa ni oruko yi?

Idahun—Ohun ti awon apa ni oruko yi, Commonwealth, ni egbe kan ti awon Gesi da sile nibe Oyinbo ti o je wi e gbogbo awon omo egbe na loti di pende kuro labe ijangba Gesi, ti nwon si ti nmojuto igbe ara won.

Ibere—Ilu melo ni o mbe ninu omo egbe Commonwealth yi ati kini oruko won ti nje?

Idahun—Mesa pere ni awon ilu ti o je omo egbe na, ti awon si je awon ilu nlanla lode aiye, oruko won niwonyi. United Kingdom (ile Gesi) ile Kanada (Canada) Australia, New Zealand South Africa, India, Pakistan, Ghana, ati Malaya. Gbogbo awon ilu nwonyi lo parapo ti nwon si fi ara won se omo iya kanna.

Ibere—Tani Olori tabi oba fun awon omo egbe Commonwealth yi?

Idahun—Bi a ba yo owo India, Pakistan ati Malaya Kuro, gbogbo awon ti o ku pata pata oba Obinrin ilu Gesi ni Olori won loni, o re ni nwon si yan lioba won, on le yan Gomina agba fun won, nitori ti awon lioba ilu na ko si papapo le lori ni oba yi yan si ipo Gomina agba fun won.

Ibere—Kini Gomina agba na yio ti ma se ise re?

Idahun—Ki Gomina agba ti a ba yan to le rise kan, enu awon asiwaju ojelu (Premier ati Prime Minister) ti ni lati ... lori iru oro be, ase ti o ba si pa ni abe ... Gesi ko gbodo kona ... re.

Ibere—E se ti Oba Gesi ko nse Oba fun India ati pakistan?

Idahun—Idi re ni wipe ilu India ati Pakistan ko sse ilu ti o ni oba, sugbon nwon gba Oba obinrin gegebi Olori igbimo Commonwealth, Olin Gesi ni nwon si nlo ni gbogbo awon ilu ti o mbe ninu egbe na.

## OLORUN KO RORO KO FI ESIN IMALE NI ENIA L'ARA

( o bere loju ewe kefa )

Gbogbo eniti o ba kirun wakati marun tan tulasi ni fun oluware ki o fa tesuba subuhanalai 33 Alhamdulilai 33 Alahuakbar 33.

A ko gbodo kirun odun tan ki a ma fa tesuba 33 beni a ko ghodo de Mosalasi odun ki a ma yan nafila, waju ki awon to kirun odun, ayafi eni ti o fe fi tire wa nkan lodo Olorun.

Lehin ti a ti kirun Alasari, a ko gbodo fi ori bale fun ohun kan, ayafi ki a fi kirun Mogaribi.

## IDUPE FUN IBANIKEDUN

Alhaji Razaki Bakare (Alobo) ati awon ebi re dupe gidigidi lodo awon ore ati ojulumo ti nwon wa, tabi ti nwon te ko iwe, tabi ti nwon te waya ranse si wa, lati fi ba wa kedun, nipa iku arakunrin mi, Alhaji Mufutawu Bakare (Alobo) eniti o rin irin ajo lo si Meka ati Medina.

NIGERIAN RAILWAY CORPORATION

TARIFF AMENDMENT

Notice is hereby given of the publication of Rate Circular No 515 amending the Nigerian Railway Corporation Tariff No. 5.

A printed copy of the Rate Circular may be inspected at any station on the Railway.

R. K. Innes,
GENERAL MANAGER.

# Awon Ara Ile Amerika Ranse Pe Awolowo

Agbo irohin wipe, omiran nko awon alatako egbe Action Group, edo foro nfa won larapa pipe ti awon ijiemi enia ranse ie Oloye Awolowo wipe ki o wa fioju kan won nigboro ilu Amerika fun alaso oro.

Awon egbe ti o se pataki bayi ko ranse pe enia kan ri egegbi iru eyiti nwon pe Oloye Awolowo yi, pipe na si je nipa mimo iyi ise ti Awolowo se.



Asiwaju ilu gegebi ti Awolowo ti o nse atilehin fun iselu, larin orisirisi eya ede, ti ko fi si ogun tabi ija, ni igbegbe re ati nibikibi, o ye ki iru enia be gba ipe iru eyiti awon ara ile Amerika pe e yi.

Ekeji ni wipe, o dabi enipe awon ara ile Amerika mo iyi Oloye Awolowo ju alatako re lo, awon alatako awonyi ti nparowo kakiri pe Oloye Awolowo ko ka awon ti o ba lo ko eko won nile Amerika kun rara.

Oloye Awolowo fi ... ori re gba iyi ati eye nilu Amerika ati kakiri agbaiye.

## IPINLE ILA ORUN TI SDI ILU OLOBA

( O bere loju ewe kini )

ti o dara ni ki ilu kan ni Oba, nitorina awon bere ki se eto lati ko Oba won jo, gegebi ti Hausa ati Yoruba Telorele, nigbati awon kolti ko oba won jo, awon oba meji ni a ngbo, (1) Oba Obosi. (2) Oba ilu Aro-suku ibiti gbogbo awon oba ilu orun ti se. Gegebi ile Ife ti je si awon Yoruba, beni Arosuku je si awon ara ilu orun.

( Iyoku di ose t'ombo )

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 467 Lagos Phone 23370